# ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 939 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 19—SEPTEMBER 25 1964 KOBO MEJI (2D)


# Awon Oyinbo Kingsway Se Saara Agbara L'Ehingbeti Nitori Obinrin Alarede Kan

EKO — Ognnlọgọ awọn enia ti nwọn farapa ni Ẹhingbẹti ni ijẹta nigbati awọn ọlọpa ju bọmbu elefin silẹ ni iwaju ile itaja awọn Oyinbo U A C ti nwọn npe ni Kingsway Stores lati le awọn oṣiṣẹ wọn ti nwọn da iṣẹ silẹ lọ. Ọ̀gá Oyinbo kan ti nwọn npe ni Peter Chadwick ti nwọn ni o gba iyawo alarede labara ni o da ijangbọn na sile.

Gbara ti awọn ọlọpa ti ju bọmbu elefin na silẹ ni olukuluku awọn oṣiṣẹ na lọkunrin ati lobinrin ba fọnka; awọn ọlọpa lu awọn diẹ ninu awọn oṣiṣẹ na ti nwọn ṣe aiyagbangba kuro ni ẹnu ọna ṣọbu wipe awọn fẹ wọle.

Ni ọsẹ ti o kọja ni awọn oṣiṣẹ ṣọbu na ti faake kori wipe dandan ki nwọn gbe Oyinbo onijangbọn na kuro lọdọ awọn. Bi nwọn ko ba gbe e kuro awọn yio da iṣẹ wọn silẹ nitoripe iṣẹ ni awọn wa se awọn ko wa iwọsi wa rara.

Fun ọjọ diẹ Oyinbo na ko wa si ibi iṣẹ afi ni ijẹrin ti awọn oṣiṣẹ na tun foju kan an, ti o wa joko sori aga rẹ loke ṣọbu na. Eleyi lo mu awọn oṣiṣẹ ju iṣẹ ti nwọn nṣe lọwọ silẹ ni owurọ ọjọ na ti olukulku wọn joko ti nwọn nwo. Awọn Oyinbo ọga wọn ni ti wọn ko ba pada sẹnu iṣẹ wọn lọsan ọjọ na awọn yio da gbogbo wọn duro.

Warawere awọn Oyinbo na ti kọwe ba gbogbo awọn oṣiṣẹ na lọwọ wipe awọn da wọn duro. Gbogbo nkan onje ti nwọn nta nibẹ ni nwọn fi ṣe saara fun awọn alaisan ni họsibitu kakiri lana.

Titi ni ṣọbu Kingsway na wa titi di ọsan ana ti a nkọ irohin yi awọn ọlọpa onikumọ ni nwọn nṣọ ibẹ. A gbọ wipe awọn oṣiṣẹ miran ni ti nwọn o ba tete pari ọrọ na awọn ni da iṣẹ silẹ pẹlu wọn.

---

**Akiyesi: Wo oju ewe kerin lori oro ti Sardauna ni egbe awon NNA ni yio se Ijoba titun.**

---

**Sardauna Boun!**

# O Ni On Kise Olorun

EKO — Ni Ọjọ Ru to kọja, Ọlala Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna ti Ṣokoto ati aṣiwaju ẹgbẹ Olomi sọ wipe on lodi si igbe ati ariwo wawa pawa, (ti itumọ rẹ tun jasi Alagbara Alagbara), ti awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ fi ki ni dide tọ de si si Eko lati bi ọjọ mẹrin sẹhin.

Ọrọ kan to jade ninu iwe irohin kan lati ọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ni Ọjọ Bọ to koja, nwọn ni ko si alagbara kan nibikan bikoṣe Ọlọrun, nitoripe ẹda ko lẹtọ lati fi orukọ Ọlọrun ṣe igberaga tabi ki o fi ṣe ọla fun ara rẹ nikan ojiṣẹ Ọlọrun ni gbogbo wa jẹ, a si nilati ma fẹriba fun aṣẹ Rẹ.

Ọlọla Ahmadu Bello ni iru asọlẹ bayi su on, ... de awọn ti nwọn ... ki enia ma fi iyin Ọlọrun ..., tabi pe awọn lọru ọ, ... amọtara ẹni nikan ... uṣe ... ti pe ... wọn yio kana.

Gẹgẹbi irohin na ti wi, ewọn ni o ṣe alaye wipe on ti gba awọn ọmọ ẹgbẹ on niyanju ni Eko lati sowọ pọ ... nwọn ... ṣe akiyesi ọrọ ti on sọ. O ni o ... igbe Pawa, Pawa, ẹgbẹ Olomi ti ... nkan miran dipo rẹ, on na si ni SALAMA.

A gbọ wipe Oloye Fani Kayode nikan ni nwọn ... oruko FANI-POWER ... on papa ... hun. Awọn aṣoju ẹgbẹ ... Imale, ... Afrika, ... Gusu Aṣalẹ ti Sahara ... ti awọn obinrin ni Eko, ... Alhaja ... Gbajabiamila ... Alhaja Tinu Kotun ... Ọlọla Ahmadu Bello ... Eko ni agbegbe ... Ọjọ Bọ to kọja.

# Awon Olopa Ibile Fe Dase Loto

IBADAN—Irohin kan ti a gbo ninu ose to koja ni ti ogbeni S. L. A. Fajinmi, Minista fun abojuto eto ilu ninu ijoba pinle Iwo Orun ninu oro kan to so wipe gbogbo awon olopa ibile to wa ni ipinle kakiri ko ni dapo mo olopa Naijiria o si tun ni " Awon olopa ibile wa da duro gedegbe fun ara won ni, ni ipinle Iwo Orun Naijiria gegebi itan Yoruba to ti wa lati igba lailai "

Oro yi ni ogbeni Fajinmi ba akojopo awon olopa ibile ti Oshun, Ife ati ti Fesha so nibi ere itowo kan ti awon se lati fi ki i ati lati fi se eye fun o si tun ba won soro pe ijoba on ti mo iyi ise ribiribi ti awon awon olopa ibile nse nipa mimu ki alafia fesemule ni ilu ati pe won yo si ri ere ise rere yi gba bakanna.

Ninu itesiwa oro re, o ni ijoba ti pinnu lati fi idi olopa ibile ododo ti nwon ti ko daradara ti nwon si itelorun mule beni ijoba yio si ma se iranlowo owo fun Kansulu ise olopa sise ni ipinle Iwo Orun.

Ogbeni Fajinmi, ki o to pari oro re, o sofun awon olopa ibile na lati se iranti ipo ti nwon wa gegebi olutosona ofin alafia ilu olupamo emi ati ohun ini awon ti ngbe ilu ati olodena iwa buburu ati jamba.

# Beyioku Nfe Iwadi Lori Wiwo Iso Oja Lainidi

EKO — Ninu iwe ikede ebe kan ti Oloye Fagbenro Beyioku to nse asiwaju egbe Demo nigboro Eko ko si Alaga Kansulu eto idagbasoke ti ilu Eko (LCC) Ogbeni Alhaji A.F. Masha ninu ose to koja, o ni on nfe ki o fojuinu wo esun kan to jade lori wiwo iso awon oloja to wa ni Ojuelegba ni Surulere pelu ika ti awon kan nse.

Oloye Beyioku ni iru iwa bayi je nkan to lo ma mu iberu wa fun titaja pelu irorun ati alafia eyiti o je ise awon obinrin oloja ti nwon ni iso wonyi, ati wipe boya nitori die ninu awon oniso wonyi ko se ti egbe Olope tabi ti Alakuko ni o mu ki LCC gbero lati gba iso wonyi lowo awon obinrin oloja na.

Asiwaju egbe Demo na tun so pe fun awon egbe oselu kan lati fi obinrin Ibo kan se oluwa lati joba lori awon obinrin to ku, iyen ki ise wipe ki awon to ku ti ki se Ibo ma le ni anfani ati ni iso lori ile won: o si be Alhaji Masha lati fi itara ati ijigiri gbo ati lati yanju oro to dele yi gegebi o ti je pe on ni yio je ipilese ati anfani fun awon to tun nbo lehin.

Oloye Beyioku tun ni on nfe ki Alaga na ri wipe ki fifi wiwo iso deruba awon obinrin oloja na de opin, beni on si nfe ki o gbe iwadi dide lori wiwo iso loja lainidi ati awon ti nwon ko ara won jo sise magomago yi ni Ojuelegba laifi ran won.

Ni ipari, o ni bi Kansulu ba ko lati gbe oro na dide, on yio kesi Minista to wa fun alafia ati eto ilu Eko lati dasi oro na.

# Ibadan Ati Egba Gbogun T'Ara Won

IBADAN — Ogbeni George Ladeinde ti awon olopa pe ni eleri sofun adajo kotu nla kan ni Ibadan nigbati Loya re na ibere wadi oro lenu re pe awon yinbon si awon Egba nigbati awon lo si abule Makore lati gbe ibe,

Oro yi ni George so nigbati ninu iwadi kan ti kotu nse lori esun apanian ti awon olopa ka si okun rin kan to nje Raimi Adisa eni odun mererin-din-logoji to nsise agbe ti awon olopa ni o pa Salawu Ogunleye ni ileto kan to nje Makore lona Eko si Ibadan ni ojo ketala osu keje odun to koja.

Nigbati agbejoro ijoba, Ogbeni Bayo Afolaju nbi lere oro, Ladeinde sofun adajo wipe oro to da a sile ni nipa ariyanjiyan to ti wa lurin awon ara Ibadan ati awon Egba abule Oke-Ona tipa nipa ibi an to nje Ileto Adegbite.

(Wo iyoku loju ewe kejo)

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI–OFE ti o kun fun irohin aladun losose.

# Abeli Fi Taba 'Igbo Pamo Sinu Iho Idi

APAPA—A gbo ipe awon ejia mefa kan ti adajo kotu keker kan to wa ni Apapa so sewon ori sirisi iye osu tabi odun ni Ojo ogun osu kejo odun yi ni awon olopa to ko wa si ogba awon elewon ni Ikoyi lati se ewon won nibe.

Nigbati nwon ko won de esu ona abawogba ewon ti awon woda si nye ara won wo lokokan boya nwon leri ohun abami lara won, beni nwon ba ri kini kan ti nwon di sugulu ninu eyiti taba igbo ti nwon iwe ni deede siga lona meta le toro ninu nailonu ninu iho idi okan ninu awon elewon na ti oruko re nje Samson Abel

Leise meji, woda kan ti oruko re nje Matthew Albert Irimoren ba tun mu elewon na lo si iwaju adajo kotu na ogbeni D. C. A. Bamgboye, o si se alaye oro na fun sugbon Samson se kanle pe iro ni nwon pa mo on, adajo ba fi osu mejila kun ewon osu mejo ti nwon ti so si tele, o si pase pe alogbekan jusile ni ko fi lo.

# E ka oro Sardauna

( loju ewe keta )

# Ogbeni Kan Gun Alupupu Dorun

Port Harcourt — Ọgbẹni kan ti oru ọ rẹ ... o ti ... ẹ mimọ fun awọn ọlọpa ni a gbọ wipe awọn ri nibiti o gbe ku si gbalaja pẹlu alupupu rẹ (Hond ) lẹba gbalasa ayi... ọna ... to wa nitosi ile iṣẹ Kingsway ni Port Harcourt laipẹ yi.

Kọ si ẹniti o mọ ohun to ṣe iku pa Ọgbẹni na, ṣugbọn ifurasi wa pe o nilati ẹ pe mọto ... kan ni o gbe ṣubu.

Lọwọlọwọ oku rẹ wa ni ile awọn dokita lakulaku fun ayẹwo bẹni awọn ọlọpa si nṣe iwadi iku to pa a.




# Tiger Bori



Omo ... ẹ N... ... Ọg... D... Tiger ... ẹṣẹ ku ... ojo, fi ... h n Ọ... Do... F... mer ... buro Ọgbẹni Ge... e F... ... fi igba ... ẹ ... aka ṣẹ ijọ M... Tiger gba lowo ... pe ara Amerika Ọgbẹni J... e G... he... e.

Tiger ... F... mer ... ẹwa ti ẹ'ubori ... (referee) ... nawọ Tiger soke wipe no ni o bori D... F... m...

E... fi ... Joe G... helce ni D... ck Tiger ... mọ ... N... ger... ko tun si ẹnikan to le ... Joe ... T... ge...

TIGER A BẸṢẸ KU BI OJO.

# Eleti- Ofe D'araba

# Adajo Onitsha Gba lejo Apapandodo

ON'TSA — Ọgbẹn V.A. S...vage to nṣe adajo ... ti k...tu ... ni O... sha ni a gbọ ... e awọn ... obnrin meji kan wọ e ... lejo ... lati baa sọro ... ori ẹjọ ... ti awọn ngbe ... wa si i aju rẹ nibti ... ti ... jọ

G...gebi alaye ti adajo S... v... ge se o ... id ... ọ ... ... sedọ ... ni ... pe w... n fẹ d... o ... wọ sẹ o ... ejọ k... n t... ọ ... seṣ fẹ m... ju o ... ọ ... ọjọ ... awọn ... le ... u ... e fun ... a ... n ... o n nu ... le on

N... g... Ọgbẹni S... v... ge bi wọn le e ... hun ti ... lepa wa sọdọ on ọ... n ninu ... ọ ... ni awọn n fẹ si ẹjọ ... n ... yio j... de fun ... ọ ... awọ ... gd... gid ... e ki e ko lat fọ o s... d... d... fun ... ọ ... wa n ... ẹ ọ n ... n ... e bi o b... gb... d... , ... on le se ... po ... pọ j... mba.

Lẹh... n elev... n ... d... o wa se ... de ... an lat fi kilọ

(Wo yoku loju e... e kẹfa)

# ELETI - OFE

(A NJU WỌN KO ŞE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P.O. Box 467 Phone 23370

VOL. XIV. NO 939 SATURDAY Sept. 19 - Sept. 25 1964


## Oro Olotu:

# Sardauna Ni Egbe OlomiNyio Pase Ijoba Titun

EKO — Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna ti Şokoto, Olotu ipinle iha Ariwa ati aşiwaju ẹgbẹ Olomi sọ nigbati o b ọkọ ofurufu gunlẹ si Ikẹja ni ọjọ Aje to koja fun ajọ awọn oniwe irohin wipe ẹgbẹ ajumọse ti nwọn şeşe da silẹ lẹnu lọọlọ yi, ninu eyiti N P C, N N D P, N D C ati M D F wa ni yio pase ijoba titun to mbọ.

( Wo yoku loju ewe karun )

## ...wọn Olosa Jalu Ilu Ilorin

ILORIN— O...n...ọgọ awọn ọlọşa ni a gbọ wipe nwọn ti wọ ilu Ilọrin ti nwọn si sọ ọpọlọpọ ile dahoro. Lara ole jija ti awọn ja ni Ilọrin laipẹ yi, nwọn ni odidi ile itaja marun ni nwọn fọ ni adugbo O...e-ita ...ọsẹ to kọja, ọpọlọpọ ẹru ati ohun ini ti iye owo wọn je ẹdẹgbẹta p ọ n u n (£500) ni nwọn ko lọ.

Nwọn ni latin işẹ buruku ti awọn ọlọşa na ti şe sẹhin, awọn irin işẹ fun ile fifọ ti nwọn gbagbọ pe awọn ni nwọn nlo fun ọşẹ şişẹ ni awọn ọlọşa na gbagbe silẹ, awọn ọlọpa si ti ko wọn lọ pamọ.

# Iwe Si Olotu

## Elewon Kan Ni Kadajo Fi Kewon On

KAFANCHAN —Ẹrin ta ku u ninu kotu Alikali to wa ni Kafanchan ni Ọjọ Abamẹta to kọja nigbati ọkunrin kan ti adajọ sọ sẹwọn ọdun kan bẹ adajọ pe ki o jọwọ şe ẹkun ẹwọn on.

Ọdoran na ti orukọ rẹ njẹ Katiyok Kofo ni adajọ sọ sẹwọn lori ẹsun jiji ẹwurẹ an ti ınşe ti Mallam Bodam Amoi ni ọjọ kẹtadinlogun oşu to kọja.

Ninu ẹjọ ti awọn ọlọpa ro, nwọn ni Kofo ati ọkunrin kan to nje "AB" wọ igu ile Ọgbẹni Amui lọ, nwọn si ri ewurẹ kan nibẹ şugbọn bi nwọn ti fẹ mu ewurẹ na ade ni Amoi ba ja lu wọn lairo tẹlẹ, ọwọ rẹ tẹ Kofo şugbọn "AB"

Nigbati Kofo na wi o ni on jẹbi ẹsun na lotitọ, nitoripe on ti jẹ ole lati ọpọ ọdun sẹhin, ati pe lotitọ AB ni o mu on lọ soe o si sọfun on lati jale.

Lehin ti adajọ ẹwọn fun tan, Kofo ba kunlẹ o si bẹ Alhaji Maule to jẹ adajọ pe ki o şe ẹkun ẹwọn fun on ki on ba le gbadun ẹmi on gidi ninu ọgba ẹwọn, nigbati adajọ si ma fesi, o ni "Gẹgẹbi oşu wọn ẹşẹ rẹ ba ti wọn to n emi yio şe da ọ lẹjọ.


BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba şepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri ra nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, ina-titan ati lati mu fi yánà Kerosine ti ọti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# Sardauna Ni Egbe Olomi N'yio Pase Ijoba Titun

( O bẹrẹ loju ewe kẹrin )

O ni bi awọn ba ie nị ijọb to mbọ ni ikawọ wọn, iru ijọba bẹ yio jẹ eyitị o dara ju, ati wipe ero on ni nigbagbogbo wịpe nịwọn ig atị aṣẹ ẹgbẹ Olomi ba si wa ni ịkawọ on ẹgbẹ na ko ni faramọ didi ajumọṣe ijọba orilẹ ede s ẹ, beni on şi duro lori ero bayi.

Ninu ịhere kan lori ọrọ ofin akan ilapa ti ijọba fẹ fi de awọn oniwe irohin mọlẹ, Ọlọla Ahmadu ni ko si ohun kan ti o n ri lati sọ ni,a ọrọ ijọba apapọṣe, nitorịpe ọrọ na kị işe eyiti o kan ipịnlẹ ịlu kan.

Aşiwaju ẹgbẹ Ol mi na tuu kọ lati m nu kan ịroh n kan nipa aşiwaju ẹgbẹ UMBC Ọgbẹni J S. Tarka ti nwọn ni o sọ pe awọn ẹgbẹ Olomi ti ranşe fun awọn ohun ija lati ilu okere fun l l lati fi j ni ipi lẹ awọn Şọsọ kị rukerudo ba le bẹ sịlẹ ni ako ko idibo to mbọ, şugbọn o ni awọn ọlọpa işe iwadi lori ọrọ aheṣọ na.

Lori y yan mej n nu awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ s po Minist laipẹ yi, Alhaji Ahmadu Bello ni on faramọ, wiw ti on si wa yi ko si n tori nkan miran b- kişepe lati wa ba Ọlọla A h ji Abubakare iroro ni lori awọn nkan ti ki işe ti u, ati lati ni anfani yiyi ilu Eko ka fun igb d n ati afẹ fun ọjọ marun pere.

Awọn ti n ọn ba wa si E o ni u ẹgbẹ rẹ ni A h i Ibrahim Biu (M ni- s a fun eto irohin ijọba Ar w ) ati Alhaji Mo a- mmed B shir ( M n sta fun eto idajọ ijọba ipinlẹ Ariwa şugbọn awọn mọ- ye ko ngbagbọ s pe w- wa ti Alhaji Ahmadu Be lo wa yi kị işeeyiti o f ramọ eto nipa idibo to mbọ ni- nu ịpari oşu kẹwa tabị nị ibẹrẹ oşu kọkanla ọdun yi.

Lar n irin ajo rẹ yi a gbọ wipe Ọlọla Alhaji Be lo yịo şe ipade iji oro n a kan pẹlu ekida awọn aşiw ju ẹgbẹ Demọ ni Eko atị pe o apa sị rọ kan ti nwọn sọ w ịe ẹgbẹ Olomi nşeto p lati şe jamba ni akoko idibo to mbọ y, o si dahun pada pe nị- tori awọn ti nwọn wi bẹ t ri ipatun wọn şwaju ni o mu ki nwọn sọ iru ọrọ yi

# Iyawo Fe Ko'ko Fe Sile Nitori O Y'ole

LỌKỌJA—Gbogbo awọn ti nwọn sa n nu ki tu ilu Lọkọja n nwọn bu sẹrin ni ọsẹ to kọja nigba ti ou- rin iyawo kan ọn, ọdun mọ dinlogun s fun ẹdọ ọ w pe ohun to fa ti on fi fẹ ọ ọkọ on silẹ nipe a tori jẹ o ja ọ ọ.

rọ yi ni eyiti obinrin na ẹnịti ozukẹ rẹ jẹ Iya vo Audu s nigbat o nr jọ nu u ko u lor ẹ ọ an to pe ọ rẹ i n u eyitị o bẹ d jọ kotu to na ni Attah Igala pe kị o tu yigi wọn ka.

Iyawo sọfun ad jọ pe gẹgẹbị deh ti ọkọ on ti şe pẹlu baba n, o ni b e o to n jẹ Oku'ẹpa Omale ti gba lati s i n i u nịtu ok baba on fun gba kan titi di igba ị o ma fi d yele akịnkan ak- kanju ati işẹ rẹ to, l a t mọ boya o le şe işe bale gẹgẹbi ẹgbẹ to jịrna.

O tun ni şugbọn iyalẹ nu lo jẹ fun on lat r pe Omale ko le tẹ b a b on lọrun gẹgẹbị ilerị adehun to ti şe iobọ ti baba o n fi pa lasẹ pe ki o n ma ba şe mọ, bi o ti jẹ pe ọ k ọ iyawo k o n i le ş ş e bị agbẹ lati ma fị gbọ bukata ile.

Şugbọn dipo rịro oko, ọkọ Iyawo sare lọ san rọ ur meta abọ ( £3 10/) fun baba va o r gẹgẹbi owo ịdana la ịg ni Iy wo t i kọ lati n a fi f rẹ f u Omale o sị pi nu lat kọ sịlẹ

N nu ẹjọ ka ị obinrin na ọkọ ti pe si kotu kekere, adajọ kọ ne ẹ lati kọ Omale s, ẹ, sị n ki Iyawo lọ sa ọ un mẹ- k dinlogun a ọ (£19 10/) pad. f u s e s jẹ y lẹnu fun on pupọ şug nigba ti O m a l e ma wi o ri ki I y a w o ba le fẹ ọkunrin kan to tị şele ị w t bu- wa fun tị o b le fẹ a, idi rẹ ni obi ri a şe pe on lẹjọ, ki şe pe on yi ọlẹ

Nị idi ey o fẹ kị adajọ vo ẹjọ na dar ko to dajọ ki o si gba w pe lati le fẹ okunrin olowo na to şeşẹ tịlu okere de ri Iyawo şe şẹ bẹ sị on, n gbati ada ẹ ma gba ẹbẹ ob arịn a, o pasẹ pe ki nwọn t n t u n ẹjọ n a gbọ ni u kotu kekere lati l e ş e iwadi to yanju.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI–OFE

ti o kun fun ir hin aladun losose.



# Agbaje Fi Egbedogbon Ponun Dibo Nibada

IBADAN — Ogbeni Salawu Ajitoni Olajide to je Kansilo egbe Demo ni Ibadan so niwaju adajo awon olopa ni Ojo Abameta to koja wipe on ati awon marun kan ti egbe ala ... sile nigbati awon gbo pe Oloye Awolowo ni egbe Olope fun Oloye Agbaje ni egbedogbon ponun (£5,000) lati fi dibo ti odun 1360 eyiti o je ti ipinle ilu ni an.

Kini o mu Ogbeni Olajide so bayi ni pe nigbati o nji ti dabobo ara re ninu kotu lori ejo kan ti Oloye Agbaje pe e ati nicu eyiti o nfe gba ... ponu ... o din mokanla, ati sile mea (£289: 3/-) lowo Olafide. Oloye Agbaje ni o je alaga ati olufi efin daboboni fun igbimo ekbe alakuko ni Ibadan.

Ninu iwe ejo gbese ti Oloye Agbaje pe o ni on fi owo yi ya Ogbeni Olajide larin odun 1961 ati osu keji odun 1962 lati fun ni anfani g-igba moto re No. L F 4848 lowo awon Oyinbo UTC ti nwon nba tunse.

Ogbeni Olajide tun dahun de on ti fe dibo yi tele ri eyiti nwon se hinu odun 1960, sugbon on faye sile fun Oloye Agbaje nigbati o seleri pe yio fun on ni edeg eta ponun (£500) ninu owo ti egbe fifun lati fi ja ifo ibo didi na.

Siwaju si, o ni on gba seki iwe owo fun igba ponun o din kansoso (£199) lona meji lowo Agbaje nigbati on fe gba moto on ni UTC, ati pe owo yi je ere ileri ti Agbaje ti se fun on siwaju ki on to foye sile fun lati dibo.

Nigbati Oloye Agbaje papa wa mbi Ogbeni Olajide ler o o ninu ap ti, Olajide gba pe Agbaje ni o se ninu owo fun ati dibo pelu iranlowo egbe Olope lehin ti nwon le on kuro ninu egbe Alakuko, ati pe awon toku pado lecin Agbaje nitoripe awon ri pe ajumosepo awon ko lo dede mo.

Ogbeni Olajide tun jewo pe lojoto ni on fi oruko Lamidi Iyanda sinu iwe ti on fi gba moto on lati UTC, nitoripe nitoto on mo pe Lamidi Iyanda ti on daruko ko le kawe beni ko si mo ko. Adajo ti fi atungbo ejo na si ojo kerinla osu yi.




# Adajo Onitsha Gbalejo ... papandodo

(O bere l oju ewe keta)

gbogbo awon ara ilu Onitsha pe enikeni to ba tun wa be on wo lona ed kodi b yi, on ko ni b ju wo ch, ki on to pase ki won mu oluware.

Ohun ti o la loye oro ikede yi ni nigbati o nfoju ... we iwe ebe ... fun gbogba duro fun lori ese kan ti awon olopa ti mu awon okunrin Hausa meta kan fun ti nwon s mu won lo s iwaju adajo kotu kekere ni Onitsha ti o si ko lati fowo si pe ki awon duro fun won.

# Reception For Nigeria's 1,oooTh Students

LONDON — Britain's Secretary for Technical Co-operation said in London yesterday he looked forward to welcoming the 2,000th student to train in Britain under British auspices "in the not too distant future". He was host at a tea-party in honour of the 1,000th Mallam Muhammadu Liman who is going to Cambridge University for post-graduate studies–at which he accepted, on behalf of the British Government, a gift of two Kano blankets sent by the Premier of Northern Nigeria, Alhaji Sir Ahmadu Bello, Sardauna of Sokoto.

"Britain is anxious to continue assisting Nigeria through the Britain-Nigeria technical assistance schemes, Mr. Carr told a gathering which included the Agents – General for Northern and Mid - West Nigeria - Alhaji A. Baba Gana and Mr. J A.P. Oki; Mr. Richard Hornby, Parliamentary Under-Secretary of State for Commonwealth Relations and representatives of the Nigerian High Commission the C R O, and the British Council.

"We also look forward" said Mr. Carr, to the day when Nigeria will be able train all her own people herself and we shall be glad to help them to expand their own training schemes to this end".

Mallam Limman, replying, said that it was not only the Governments of Nigeria but the people as well who appreciated the importance of the role Britain was playing in the country's development. Britain he pointed out, was helping not only through education but also in many other ways.

## A Visit To Kew

Banana trees and cocoa plants made Mallam Muhammadu Liman feel at home when he visited the famous Botanical Gardens at Kew London on Monday.

There and at the nearby Commonwealth Mycological Institute which deals with fungus diseases Mallam Liman was able to see how British experts are helping to solve the horticultural and pest problems of the Commonwealth countries.

Of particular interest to him were some cocoa plants which are spending some months in quarantine at Kew before being sent on to Nigeria.


PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of sidings) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns, all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 200 and more stations.

And what's more : you are dealing with people you can trust.

SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL







# Nwọn Fẹ Ti Ile Iṣẹ Ero Gbohungbohun Kakiri Ipinlẹ Ilu

ENUGU—Awọn ile iṣẹ ẹrọ gbohungbohun ti nwọn w ninu awọn ilu ni ipinlẹ mẹrẹrin ni a gbọ wipe nwọn fẹ ti pa laipe yi gẹgẹbi irohin kan ti a gbọ lati Enugu.

Apẹrẹ ọrọ yi ni Oloye T. O. S. Benson to jẹ Minisita fun eto nipa irohin fun ijọba apapọṣe fi han ni Enugu ni Ọjọ Aje to kọja nigbati o ndahun si ibere kan lati ọwọ awọn oniwe irohin ni kete ti o de si Enugu fun ipade igbimọ ajiroro ẹgbẹ Alakukọ.

Oloye Benson ni nigbati awọn Minista lati ipinlẹ mẹrẹrin ti nwọn wa fun eto irohin fun ijọba ipinlẹ wọn ba pade ninu oṣu yi, wọn yio sọrọ nipa ọna ti nwọn le gba fi ti awọn ile iṣẹ ẹrọ gbohungbohun na pa, nitoripe ninu ọkan awọn ile iṣẹ wọnyi dabi ile idẹra ti ko nidi nwọn a si ma lo wọn lati ma fi kede aketunke ti ko ti lẹ ba leti mu rara,

Nipa awọn oṣiṣẹ ti nwọn ba da duro nibẹ nigbati nwọn ba ti ile wọnyi pa, Oloye Benson ni ile iṣẹ titun kan ti nwọn fẹ da silẹ laipẹ yi yio mu ki ọpọlọpọ wọn riṣẹ ṣe ṣugbọn lori asiko ti ile iṣẹ Agbaaṣiwaju ajumọṣe ẹgbẹ awọn tẹ Iwe Irohin fun ilẹ Naijiria titun na le bẹrẹ o ni ijọba apapọṣe ti ṣe ipinnu lori rẹ ati pe nwọn yio da silẹ ni kete ti owo ba ti dele.

A gbọ wipe awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ ẹrọ gbohun-gbohun ni Eko ni nwọn ti da iṣẹ silẹ bẹ i nwọn si ti ke si ijọba Apapọṣe lati gba iwa d d de fun fifi oju inu wo gẹgẹbi nwọn ti nṣe eto iṣẹ si nibẹ papa larin awọn ti nwọn jẹ ọga agba ile iṣẹ ẹrọ gbohungbohun ti Ibadan nikan ti o jẹ eyiti o si nṣe daradara awọn to ku ti faake kọri.

Ọgbẹni Odugbemi to jẹ akọwe ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ wọnyi ti gbogbo asiri aiṣedede ati iṣẹ buruku ti nwọn nbo mọ'ẹ nibẹ ..I iwadi na yio tu jade ati pe kaka ki nwọn pana dida iṣẹ silẹ yi to ti bẹrẹ bi ọjọ mẹrin sẹhin nitse ni nwọn nfi awọn oṣiṣẹ ṣe fari o si wa jẹ ohun iyanu fun awọn lati ri iru owo pupọ ti nwọn nsan fun ọka awọn oṣiṣẹ wọn to wa ni ile iṣẹ Tẹlifiṣọni.

Awọn oṣiṣẹ na ni awọn nfẹ iye owo oṣu to to dara fun awọn to mọ nipa iṣẹ ẹrọ titun aye iṣẹ awọn oṣiṣẹ ṣe ati ni mu iwe gbi gbe lọ si idalẹ ti nwọn ti fi fun awọn to jẹ oloye ninu ẹgbẹ wọn ṣugbọn a gbọ pe awọn olotu ile iṣẹ lori eto awọn oṣiṣẹ ati awọn oṣiṣẹ ti ko ẹsẹ bọ ṣokoto lati fi opin si rukerudo ọrọ yi.

---

## British General Election Next Month

LONDON—The British General Election will be held on Thursday, October 15.

This was announced from 10, Downing Street yesterday by the Prime Minister, Sir Alec Douglas Home when he returned to London after seeing the Queen at Balmoral Castle.

The present Parliament will be dissolved on Friday, September 25 and the new Parliament opened on Tuesday November 3 following the election of the Speaker and the swearing in of members which will take place at Westminister a week earlier.

The present Parliament will not meet again, although there is provision for it to do so until Dissoltion if the need should arise.

# Owo Aiyederu Gbe Alufa Ati Awọn Mẹta De Kotu

ỌYỌ — Aṣiri — awọn oni madaru to ninu kotu kekere kan ni Ọyọ ni ọjọ Bọ to kọja nigbati awọn ọlọpa ko awọn ẹru irinṣẹ ti nwọn fi nṣowo aiyederu wa si kotu bi idẹ, ati waya, irin ootu, faili ati orisirisi iwe miran ni ọjọ ti nwọn bẹrẹsi ṣe iwadi lori ẹsun mẹta kan ti awọn ọlọpa ka si Alufa Ṣọṣi kan ati awọn agbẹ mẹta lẹṣẹ.

Ọgbẹni Solomon Adewunmi to jẹ Alufa Ṣọṣi ati Lasisi Ẹgbẹyẹmi, Buari Kolade ati Ilọri Akanji ni awọn ọlọpa mu nitoripe nwọn ri ẹyọ ṣile marun din ladọrin owo aiyederu lọwọ wọn lailẹtọ tabi lọna ti ko tọ suna ni ilu kan ti nwọn npe ni Ilọra nitosi Ọyọ ni ọjọ kejidinlogun oṣu karun ọdun yi.

Ọlọpanu Olokun meji kan Ọgbẹni Iyiọla Benson ni lori irohin kan ti awọn gbọ, on ati awọn ọlọpa miran lọ yẹ ile awọn mẹrẹrin wo, ati pe larin iwadi ti nwọn tun nṣe, Ẹgbẹyẹmi ati Kolade jẹwọ fun awọn pe Alufa Adewunmi ni Olori awọn, nitoripe ọmọ ẹkọṣẹ ni awọn jẹ lọdọ rẹ ninu iṣẹ ṣiṣe owo aiyederu.

Ọgbẹni Benson Ọlọpanu na tun sọ pe nigbati awọn kori nkan efin mu ninu ile gbogbo wọn, awọn ba lọ yẹ abule oko wọn wo nibiti awọn gbe ti ri awọn irinṣẹ ti nwọn fi nṣowo ati owo ti nwọn ti ṣe pari ko ti nwọn si ja ewe bo lori.

Awọn mẹrẹrin sẹ kanlẹ pe awọn ko jẹbi ẹsun na adajọ si gba pe ki nwọn wa oniduro wa ni ọgọrun pọnun titi on mi fi tun ẹjọ na gbọ ni ọjọ kejidinọgbọn oṣu yi.

---

## Ara Ibadan Ati Egba Gbogun Ti'ara Won

(O bẹrẹ loju ewe keji)

O si tun dahun pe idi ọrọ yi ni on ati awọn kan fi ko agbako ẹjọ kan lori eyiti awọn ọlọpa mu wọn fun ẹsun pipa ara Ibadan kan to ku larin ọdun 1957 ati 1958, ṣugbọn ti adajọ sọ pe on ko jẹbi.

Ladẹinde tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe ninu ọdun 1962, awọn Ẹgba pe Sanusi Alaka ati awọn miran lẹjọ ninu eyiti nwọn ni awọn ni awọn miran lẹjọ ninu eyiti nwọn ni awọn ni ilẹ to daja silẹ yi, awọn si gba idajọ wipe awọn ni ilẹ na tọsi, ati pe ni ọjọ kẹtala oṣu kẹfa ọdun to kọja, on ati awọn enia on pẹlu awọn Ẹgba tun pinnu lati jọ ma gbe ori ilẹ na, ṣugbọn nigbati awọn ara Ibadan ri wipe awọn fẹrẹ de ibẹ awọn ba ṣi ina ibọn bo awọn.

Alaka to jẹ aṣiwaju awọn ara Ibadan ni o kọkọ fi ibọn ṣe Ogunlẹyẹ lẹṣẹ, o si ṣubu lulẹ, lẹhinna ni Adisa ba bẹrẹsi ṣa Ogunlẹyẹ lada lori ati lara eyiti o mu ki o ku bamubamu, nigbana ni adajọ wa fi atungbọ ẹjọ na si ọjọ keji oṣu kewa ọdun yi.

---

# E ka oro Iyawo to ko oko re

( lojn ewe keta )

---

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos,